EJO IGA IDUNGARAN NI ILU OYNBO



SEE YOU PAY THE
CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO



AWOGBA Omode fun Giri, Ete, Hihu-ehin, Orere. Ra Ti ... Ile Egbogi — 15? — Oledina ... Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS

VOL. No. IX 519. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MAY 11, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

# EJO MOBA DI OLOGBE

MỌBA. A gbọ irohin wipe, igbo kan wa li eti Abule Mọba niwaju Oke Ipa ti nwọn pe ni Igbo-ejo. Ninu igbo yi ni orişirişi awọn ejo wa tobẹ ti o jẹ ewu fun ẹniti o ba wọ igbo na. Pẹlupẹlu ninu igbo na, akọ ejo kan nbẹ ninu awọn ejo inu igbo na ti o ma gba ẹbọ lọwọ awọn ara Mọba lọdọdun.

Lasiko ti awọn oyinbo nkọle si Ikoyi iwe de wipe laria igbo yi gan ni awọn ni lati kọ ile nla kan si. Oyinbo ti o nkọle paşẹ fun awọn lebira lati şan igbo na, şugbọn nwọn taku pe awọn ko le şe e, awọn sọ pe ejo pọ nibẹ. Oyinbo ranşẹ lọ sọ fun babalorişa ti o nsin awọn ejo na pe, ki o yara ko awọn ejo rẹ lọ sibomiran, nitoripe on fẹ lo ibẹ.

Babalorişa na sọ fun Oyinbo na wipe, ki o lọ ba awọn ejo na sọrẹ nitoripe nwọn li eti. Oyinbo na mu suru ọsẹ meji koja, o paşẹ pe ki awọn lebira lọ şan igbo na, sibẹ awọn tun taku.

Nigbayi ni inu wa bi oyinbo na, o pada lọ sile, nigbati o ma fi pada de, o mu kini kan dani, o dabi raketi, nigbati o rin sunmọ eti igbo na, nşe ni raketi yi gbinọya.

Bi ile ọjọ keji ti mọ oyinbo ni ki nwọn bẹrẹ si şangbo, gbogbo awọn ejo inu igbo na loku, eyi ti o tobi larin wọn si gọ si ọna mẹrin. Lati ọjọ na ni igbo ejo ti parẹ ni Mọba.




THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital — £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

# Ejo Iga Idunganran ni ilu Oyinbo



Lọya Dingle Foot, ẹni ti ọmọ Oyeka ... agbẹjọro niwaju Privy Council ni ilu Oyinbo

Lọya na sọ wipe, lọjọ kini oşu October ... 1949 ni Ọba Adele wọ inu Iga Idunganran pẹlu ogunlọgọ awọn enia lẹhin rẹ, nwọn fi agbara fọ ilẹkun awọn si wọle, ibẹ lo si wa titi latigba na wa. O ni on fẹ ki awọn adajọ na mọ wipe, Ko si oye Ọba Eko tẹlẹ ri latigba ti awọn ti şe adehun pọ ti awọn si gba ilu Eko si abẹ abo Gẹsi, şugbọn nwọn ma nsaba lo o ni ida kokan.

Nkan ti awọn nro ẹjọ yi le lori ni wipe, on fẹ gba Iga Idunganran pada, nitori ti baba on ni, on si nfẹ gba ẹgbaa Poun fun lilo ti ọba Adele ti lo o.

Lọjọ 6th oşu August 1861 ni ọba Dosunmu ba aşoju Gesi şe adehun pọ ti awọn si fi ilu Eko si abẹ abo ijọba Gẹsi. Nigbati o si di ọjọ 15th oşu July 1870 ni ijọba Gẹsi şe gọnrandi Iga Idunganran fun ọba Dosunmu. Latigba na wa ni arọmọdọmọ ọba Dosunmu ti njoye sinu Iga na ayafi ni ọdun 1925 si ọdun 1931 nigbati ijọba fi wa Eşugbayi Eleko lọ si Ọyọ.

No. 61.

# Ile Alaisan ni Ebute-meta ati ile Alabiyamo nita Eleiye

Minister ti Social Services lo ni ki a se ikede yi Nwon fi oro kan han mi, ninu iwe irohin ti ajade lojojumo nile Eko, lojo 27th osu April 1957, anu se mi pupo lati so wipe, eniti o ko iwe na, ko gbo idi oro na daradara ati wipe, ko ye to, nitori Isoro yato si ise, eniti o kowe na, le so ohun ti o wu, sugbon bi oro na ti lo niyi.

Nigbati iwe nipa eto ilosiwaju ise isegun jade ninu igbimo House of Representative ninu osu March 1955, Ijoba fara mo eto inu iwe na, gegebi owo ti wa nile si, Iyen ni wipe laisi owo lowo, ko si ise kan ti a le dawole. Ko si owo nile fun ilosiwaju ise isegun titi osu March 1956 fi de. Nigbati igbimo fi owo lele fun awon nkan awonyi, opolopo ni awon nkan ti owo inu re yato si eto ti o ti wa nile ri ninu odun 1955. pelupelu, ninu odun 1956 si 1957, ijoba ko fi owo lele rara y la fun ile Alaisan l'oke Ebutemeta tabi ti ile Alabiyamo titun ti a fe ko.

Minister ti o nse Olotu ile kiko fun Ijoba ti yan awon Kole-kole (Contractor ti yio sise lori iba owo ti a ba ri, nwon si ti mura lati gbale ni Surulere fun ile titun na, ti yio si tobi to lati gba awon alaisan ile mejeji ti a daruko siwaju. Ninu osu September 1956, ni a pete nipa ona ti moto yio magba dele alaisan na, nwon si mu iwe na wa fun ayewo lati odo Kole-kole, ti awon osise Public Works Department.

Nigbati a si ye iwe na wo, a ri wipe yio na wa lowo tayo iye owo ti ijoba fi lele lo, nigbati ko si si owo lowo lati ko iru ile be, a so fun Kole-kole na ki o tun iwe na se ki owo re mase tayo iye owo ti ijoba fi lele lo. Ogbeni Grey, ti o wa nibi ise awon Watkins Grey & Partner ni yio ko ile na, o si ti de si ile yi nipa ile na. Bakanna ni awon Lands Departments, ngbiyanju lati wa ile ti o to bi gidigidi ti yio to 92 Acres ni a pa Surulere, ti yio gba gbogbo alaisan toke Ebutemeta ati awon Abiyamo Ita Eleiye. Nse ni awon mejeji yi yio fi egbe kan egbe, sugbon olotu ototo ni yio ma se akoso won. Awon Public Works Department ti lo se ayewo apa ibiti nwon nfe kole na si, bi o ti lagbara to lati gba oju agbara, omi ero ati ina lentriki ati eto igbonse. Ona ibiti a le gba de ibi ile na nisisiyi, je ona tooro kan sugbon nwon ti so fun oga ile ise, L. E. D. B. ki o se oju ona ti o fere to ogoji ese, ti yio si gba moto lati mu enia de ibe gbogbo eto awonyi si ti setan nwon ti fi tender sode fun awon ti yio san igbo ti yio si tun apa ibe se, ko ni pe pupo ki ise na to bere.

Ile iwosan ti a fe koyi, yio wa fun opolopo ile ijoba ati awon ile ise miran ti ko nse ti Ijoba, gbogbo won ni lati sowopo fun ilosiwaju ile iwosan na. Bi a ba fe ko aragbabu ile bayi o ye, o si to wipe, ki a fi ara bale wadi ohun gbogbo ti o jemo ara re daradara, a ko gbodo fi ikanju bere re, de ipe ti ao fi pari re ni pajawiri, o to ki e gba asiko die.

Nisisiyi, ijoba ti gba wipe, eto ni ki a tete ko ile alaisan miran, fun anfani ogunlogo awon enia ti o nlo si ile iwosan ti Eko nibiti aye ko gbani to ati ile alabiyamo fun ti awon ti o nwa lati ile won wa gba egbogi ati awon aboyun ati pelu itoju awon majesi. Ati gba ile kan si Ita Eleiye (Massey Street) ati ekeji si adugbo (Oke-arin John Street).

Awon osise Public Works Department ti se eto nipa ilana bi ao ti se ko ile na ti yio gba gbogbo awon alaisan ti o ati ile wa, awon aboyun ati awon majesin pelu,

Ko ni pe rara ti ao fi bere si ko awon ile na Aye ti o ba si silę ni ile iwosan ti Eko, (General Hospital) nigbati a ba pari awon ile nwonyi, yio tun sipaya sile fun lilo ti ao gba sile iwosan wa,

No. 63

## Constitutional Conference

At the request of the Secretary of State for the Colonies, it is notified for the information of those persons or organisations who will not be directly represented at the Conference but who wish to make written representations for consideration by the Conference, that the following procedure should be followed :

1, Documents should be sent to :

(i) The Chief Secretary of the Federation ; or

(ii) The Deputy Governor, Ibadan; or

(iii) The Deputy Governor, Enugu ; or

(iv) The Civil Secretary, Kaduna for onward transmission to the Secretary-General of the Conference.






# Iya Bele o, Ile Lo Lo Tarara

ABẸOKUTA. Ẹsẹ ko gbeji ni bi iku Iya wa Sẹliya Ọlabisi, ọmọ Ṣokeyinbo ni adugbo Igbore ni Mọlọdẹ Abẹokuta.

Ẹsẹ awọn Alhadji pe, awọn Lemọmu ati awọn Alufa. Lẹhin ti awọn ti sinku na tan gẹgẹbi aṣa Imale tan awọn ṣe wasu itunu fun awọn ọmọ Oloku, awọn si toro ikẹ ati igẹ fun awọn ọmọ ti oku na fi silẹ.

Awọn alejo ti o wa sibi oku na lati inu ẹgbẹ Nawo-Adinni Ibadan, Eko, ati lati Ijẹbu ko niye.

Awọn ọmọ oloku niwọnyi:–

Ọgbẹni M. Lawal, A. Lawal A. Bruimo; R. Ọlalekan ati Adamọwun. Ọba ko feri ji oku na o.

# C. D. Akran



Eni ti a nwo ninu aworan yi ni Oloye, olola C. D. Akran ti Badagry, o si je okan ninu awon Minister agbegbe Iwo Orun Nigeria. O je okan pataki ninu awon iko egbe Action Group.

# Deji Akure di ologbe

AKURE. O ṣe bi ẹ ti wu ki o ri, ọkunrin ni lati lọ si ile rẹ pipẹ. Ni owurọ ọjọ ọsẹ ọjọ 5th oṣu May ni a gbọ iku Alaiyeluwa Deji ọba Akuẹ wipe o ṣalaisi nigbati o di ẹni ọgọfa ọdun.

Ologbe ọba yi jẹ ọkan ninu awọn igbimọ lọbaIọba ilẹ Yoruba, on ni baba ẹgbẹ igbimọ ile Akurẹ on kanna ni adajọ agba ninu kotu kotẹmi lọrun.

Ẹni ọgọta ọdun ni alagba ọba na ki o to joye ọba, o si lo ọgọta ọdun lori oye ọba na, adọta lerugba ọmọ lo fi silẹ nile aiye, adọjọ iyawo lo si fi silẹ.

Nigbati okiki iku rẹ gboji kan kakiri ilu, nṣe ni gbogbo awọn Onisowo pa ilẹ kun wọn de titi ti nwọn o fi ṣe oku ọba pari. Gẹgẹbi aṣa iṣẹ dale ilu Akurẹ, bi ọba kan ba ku, gbogbo awọn igi ti o mbẹ ni nwọn o bẹ lulẹ.

Oriṣiriṣi awọn ijoye, ọlọla Minista, ati awọn gbajumọ nile, loko, ati lokere gbogbo lo ti bẹrẹ si wọlu fun ati sinku ọba ti o goke alọ.

Gẹgẹbi aṣa iṣedale, bi ọba Akure ba ku bayi nilu Oke-Ile ni nwọn o gbe lọ sinku rẹ, nitori pe ibe je orile fun wọn lati ibe ni nwọn ti wa tẹ ilu Akure do.

# Owe Ajapa ati omo re

Ni irọlẹ ọjọ kan ti oju ọrun dara, ti afẹfẹ nfẹ ti awọn ẹiyẹ si nkọrin, Abawun Ajapa ati yanrin bo iyawo rẹ. ati ọmọ rẹ joko si ọdẹdẹ ode, awọn nmu faji ọrọ siso.

Nibiti awọn nsọrọ yi lọwọ, bẹni ọkunrin kan gun ẹṣin sare kọja lọ lojude Ajapa, Ajapa dide kian, o bọ sode o nwo ẹlẹṣin na bi o ti ngun sare lọ.

Ajapa wọle tanu-tanu Yanrinbo si ri loju rẹ pe ohun kan nṣe ọkọ on. O bere lọwọ rẹ pe, kilode ọ ti o fi koro oju bayi, kini ohun ti o de?. Ajapa dahun pe ṣe iwọ ri ọkunrin ti o gun ẹṣin kọja nihinyi, o nlọ si ajo ni, nigbati emi na ba ko esusu mi, ẹṣin ni o ngo fi ra ngo ma gun lọ si oko, ile ọba ati si awujọ.

Ọmọ Ajapa dahun pe, Hanin! baba mi yio ra ẹṣin, bi mo ba ta gun u ngo ma fi sare, kutupa! kutupa! kutupa.

Ibẹ ni Ajapa ti lọ ibosi to-o-o, o wipe yẹ, yẹ, yẹ! kiola! ọmọde yi fẹ pa ẹṣin mi, bẹni o fa ọmọri odo yọ, o si sẹ mọ ọmọ rẹ li ori, ọmọ na si ṣe yakata, o si ku.

Gbogbo awọn ẹniti ọrọ na ṣoju rẹ kebosi to wipe, Haba iwọ Ajapa, kini ọmọ na ṣe fun ọ ti o si fi lupa? Ajapa dahun pe, nṣe lo fẹ gun ẹṣin mi pa gbogbo enia si bere pe ẹṣin na ha da? o di wọmi nwo ọ. Bayi ni Ajapa padanu ọmọ rẹ lori ohun ti koiti ni rara, Ibinu ko da nkan, Suru ni baba iwa.

# Opidan kan pa ara re

KANO. Ọkunrin opidan kan ara ilẹ Kanuri ti nwọn npe ni Sanni lo de arin ọja Kano ti o si bẹrẹ si pa oriṣiri idan ti gbogbo enia si pe le lori. Bi o ti npa awọn idan na loriṣiriṣi, ni ọkan ko jọ ọkan, nṣe ni gbogbo awọn enia nho ge-e, ti nwọn si npatẹwọ bi o ti npa awọn idan na.

Nigbati awọn enia pọ tan ti nwọn nworan opidan yi, nigbana lo fa ọbẹ oloju-meji yọ o fi rẹ ara rẹ lọrun, ṣugbọn ko ran a, o wa gbe ọbẹ yi kanna lo ara rẹ ni agbẹdu, o yun lakọkọ ko ran a, nigbati o yun-u nigba keji, pipe ni agbẹdu rẹ bẹ ti ẹjẹ daro mọ ifun inu rẹ, nṣe ni nwọn gbe lọ si ile alaruo.

Bi agbẹdu ba ti bẹ, ifun si danu ko si ṣiṣẹ. Ọlọrun ni lati gba alejo.

# Owe

Ko dun mi, ko dun mi, agbalagba mbu opa'ẹmẹfa nitori iyan ana.

## Irohin Ogun Eleduwe

Lẹhin ti Balogun Afọnja ku tan awọn ara ilu Ilọrin wa lọ gba ogun awọn Fulani, Hausa ati awọn ara ilẹ Kontogora jọ lati gbe ogun wọ ilẹ Yoruba.

Ilu Ikirun ni awọn kẹkẹ Şieun si şugbọn Balogun Fulani dahun pe, ilu Offa ni awọn o lọ, ki apakan lọ si Oshogbo, şugbọn o pasẹ pe ki Balogun kara nişo ni Oshogbo.

Nigbati ara Oshogbo gbọ nipa ogun Fulani, nwọn ranşẹ lọ si Ibadan Lalfi jafara ogun Ibadan dide, awọn ja ija na pẹlu agbara Okuarin, awọn si le ogun Fulani gba ọna ilu Ilobu.

Ogun Ibadan tun lepa wọn. Nigbati nwọn de ibikan ti a npe ni Eleduwẹ nibẹ ni awọn Fulani tun duro je, ọkanrin ọdẹ kan ti a npe ni Erinlẹ le şe akọni loju ija lọjọ na. Balogun Kara lo siwaju ogun Fulani lọjọ na, ọwa iria lo si wọ. Kolti si ibọn lasiko na, ọfa, ọkọ, kondo, kumọ ni nwọn fi nja. Ogun Ibadan ko le şi awọn Fulani kuro ni Ilobu. Opẹlọpẹ ọdẹ Erinlẹ le ta ọfa ba Balogun Kara loju ki ogun Fulani to şi kuro ni Ilobu. Eyiyi lo jẹki Erinlẹ di orişa akunlẹbọ ni Ilobu titi di oni yi.

### ORIN IFA

O gberilẹ o je ku o
O gbetilẹ o jeja
O gberilẹ o ọkun apako
Şoranti ile t.a je ma

## Awọn Ara Togoland Nwa Ija Aganyin

Ọgbẹni Ako Adjei ti o şe aşoju (Minister) fun awọn ilu okere labẹ ijọba (Ghana), şe wipe, rogbodiyan ti awọn ara ilẹ Togoland afa lẹsẹ yi je isọlẹnu fun awọn Aganyin (Ghana). O sọ ninu igbimọ wipe, bi awọn ọnikan ba nfa ijọgbọn lẹsẹ bayi ki iru awọn ọnia bawọnni maşe jẹki o ya wọn lẹnu nigbati ọkunrin meji ba foju rinju ara wọn.

Ọgbẹni na tun fi ye igbimọ wipe ninu rogbodiyan ti awọn ara Togoland afa lẹsẹ yi o di enia marun ti awọn lupa ọgọrun enia lo fi ara şeşe enia marundinladọta diniriowo ni ọwọ ọlọpa ba lasiko rogbodiyan na enia meji lelogoji din nigba le jẹbi niwaju adajọ ẹgbẹsan le mejidinlegbẹta ibọn ni awọn ọlọpa ri gba lọwọ wọn. Ohun ti o fadi rogbodiyan na niyi.

Ninu oşu February te koja lọ yi ija na bẹrẹ lori o şe ọrọ ilu ko şe ọrọ ilu ọrọ na si ti wa nilẹ lati ọdun 1950 nigbati awọn apakan wọn fẹ gedegbe awọn apa keji ko si fẹ. Şugbọn awọn ti o nle pọnrọn ninu ija yi ni awọn ti a ti lọ gegẹbi a tişe nlo awọn ohun ija akan pupọ ni nwọn si baje lasiko igba ti Ghana ngba ominira. Nitorina on da nimọran ki ijọba fi aşẹ si lati ba je awọn jandiku na niya.


*Family links with*

## THE UNITED AFRICA COMPANY LIMITED

*Recording some of the many families who have found interesting, varied and worthwhile careers with U.A.C.*

After a long and happy career with The United Africa Company, Daniel Foluso Ayorinde Majekodunmi retired on a pension in 1955. Now successfully trading on his own account, he is a valued customer of U.A.C. Motors. Among the many cherished memories of his 27 years with the Company, Mr. Majekodunmi recalls with pride how U.A.C. presented him with a Gold Watch in honour of his loyal and meritorious service; and how in 1954 his son Edmund was awarded a U.A.C. Scholarship.

*Many other members of this family have taken up careers with the Company, including the popular high jumper Josiah Olatunji Majekodunmi. Their total service amounts to over 150 years, with many more to come. This is a fine record which the Company is glad to acknowledge.*







**The Majekodunmi Family**

**Record of Service of the Majekodunmi Family**

| | |
|---|---|
| D. F. A. Majekodunmi 27 years' service | J. Majekodunmi 13 years' service |
| M. A. Majekodunmi 31 years' service | Josiah O. Majekodunmi 8 years' service |
| J. K. Bankole 21 years' service | A. Majekodunmi 7 years' service |
| J. O. Idowu 19 years' service | O. A. Majekodunmi 6 years' service |
| F. A. Majekodunmi 15 years' service | James O. Majekodunmi 4 years' service |




Our pictures show some of the Majekodunmi Family working for the Company

## Owo panu ile lo poju

OLOTU,

Gegebi ogbeni kan ti bere lowo mi wipe, owo kinni eyiti enia dudu ba awon oyinbo se pupoju. Ogbeni na ni ki a daruko nkan meji
(a) Owo panu ori ile
(b) Owo Iso

Ohun ti o feki nse be ni yi wipe, ni odun 1908, ti mo lo si Ibadan o fere je wipe gbogbo ile ti o mbe ni Ibadan ni ile koriko. Gegebi o si ti mo pe ile Ibadan poju Eko lo, nigbati mo tun pada de ilu na ni odun 1926 nko fi oju ri ile koriko kan. Mo si fi inu sire iye awon Iso ti nwon o fi kan awon panu na mo [ri pe ko n se owo kekere ni awon se sibe.

Enikeni ti o ba si ri oye ilpe, on mo ohun kan ti awon oyinbo fi sowo ti o poju panu ile ati iso lo, ki o kowe re ranse siwa fun titejade,

Emi ni J. J. Jenkee

## Imoran Awolowo ati Ribadu dogba



Awon mejeji ti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Olola Awolowo ti o nse Prime Minister fun agbegbe Iwo Orun ati Malam Muhamed Ribadu, ti o nse okan ninu awon Minister ile Oke Oya. Nigbati oro awon mejeji papo ni nwon gbowo lowo ara won, nipa bayi, eyi mu wa ni ireti wipe, nkan yio senu re ninu igbimo ti nwon nlo se nilu Oyinbo ninu osu yi.

## Ijoba ti bere si pin ile pada fun awon Onile

Awon Igbimo L.E.D.B. ti bere si pin ilẹ pada fun awọn ti o ni ilẹ na. Ọgbẹni J. W. Handerson ti o nṣe olotu igbimọ yi sọ wipe ni Plot I ati ni Plot II o to iwọn ogoji ilẹ ti a ti pin pada fun awọn onilẹ, gẹgẹbi ohun ti ijọba ilu Eko fẹ wipe, awọn ti o ni ilẹ ibẹ gan ni ki a pin ilẹ na fun pada.

Titobi ilẹ na, ati iye owo ti nwọn ma san, bi o ba to asiko, no gbe jade. Ọgbẹni Henderson tun sọ wipe, owo ọya ti nwọn fi tun agbegbe na ṣe, ko ni pọ ju ida merin iye owo ti nwọn fi kọ lọ.

Gẹgẹbi ae ti ṣe pin ilẹ na, mbẹ lọwọ awọn igbimọ kan ti ijọba ti yan fun iṣẹ na, lati jijadu fun afani awọn onilẹ lọdọ ijọba.

(Wo iyoku loju ewe kefa)



## Awon Oniwe Irohin

Aworan enia ti a nwo nwonyi ni awon Oniwe irohin ti ijoba ko lo silu Oyinbo, nwon ya aworan nigbati nwon nkoja lo li opopo ibiti nwon nte iwe irohin ni ilu Oyinbo.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
29, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 519, LAGOS, SATURDAY MAY 11, 1957


## Alo re, abo re, alobo

Orin awọn Ijọ Onigbagbọ yi ni ao fi jẹ oml toro ọrọ s'nu Iwe irohin wa ti ọsẹ yi fun awọn olotu wa ti nwọn nlọ si ilu Oyinbo nlaa ọsẹ yi lati lọ] gba ominira bọ wale fun gbogbo wa. Orin na niyi:-

"Ẹnyin aro, nibo ni ẹ nlọ,
Ti ẹnyin tọpa lọwọ nyin ?
A nlọ si afin ọba rere.
A nlọ si afin ọba rere
A nlọ sile to dara

Nitа ṣoki, gbogbo wa lo oka a ninu iwe irohin jakejado nipa wahala ti awọn oṣelu wa tiṣe lati ẹhin wa nipa wipe nwọn fẹ bọ ajaga kuro lorun gbogbo awa enia dudu, ki nwọn si mu wa kuro loko ẹru, ki iwọ ati emi le ni idẹra ati awọn ọmọ ti o mbọ lẹhin wa pẹlu.

### ORIN NI OHUN ẸGBAJI

Ẹ ba tete wa kalẹ,
K'alọ k' Awolọwọ onlnure ] 2
On lo wẹkun wesa
T'o m'ọpa bọ wa sinu ile
Oju gbogbo wa lo ṣe
On lo m'ọba gunwa
Toba fi njo
On lo l'akun la'sa
P'oju on l' Eko a roju
Ọba Oluwa ko ṣọ ẹ
Wa jere l' Eko wa si rere jẹ
K' Oluwa fẹ wa rire Eko laiye

Iṣẹ ajo yi ni awọn Olotu wa ko sinu ọkọ, ti nwọn lọ yi, Alọ re, abọ re Alọbọ Ki Ọlọrun ṣọ wọn lọ, ki o si ṣọ wọn bọ.


### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Ẹnyin abiyamọ ewa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun ọtutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko enin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun ọmo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodọ :-

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS


## Ijoba ti bere si pin ile pada fun awon Onile

(O bẹrẹ loju ewe karun)

Ijọba ti pese aye ibomiran silẹ larin ilu Eko fun awọn onilẹ ti ko ri aye ilẹ gba nibiti a ti le wọn kuro lakọkọ.

Ibiti a npe ni Sub-area I ni apa Broad Street, Martins Street, Breadfruit Street ati Layeni Street Sub-area II ni apa Broad Street, Balogun Street, Breadfruit Street ati Martins Street.

Alhadji A. F. Masha so wipe inu on ati awọn enia on dun pupọ si awọn ilẹ ti ijọba fẹ da pada fun awọn onilẹ.

### Orin Bisi

Eni bimọ t'on doro 2.
Oro ti ẹ gbin ti ẹ si keko de,
Bo pe titi, asa hu lori ẹmẹ;
Ko dan wa,
Oro t'enda ko dun wa
Bo ya ẹjẹ la bikan silẹ
Eni bimọ t'on doro

## Enyin Agbe Eni Nyin Melo?

Afara ni ija ẹkan, egun ti arọ ba ti gbọ tẹlẹ, o daju pe ko ni pa arọ na. A nṣe ikede fun ẹnyin agbẹ nipa kokoro eṣu wipe nwọn ti wa bẹ ilu Kano ati Jos wo.

A gbọ wipe bi nwọn ba kuro ni, agbegbe ti a darukọ nwọnyi, a ko mọ ibiti nwọn tun le dari si. Ko nṣe jamba kekere ni awọn ṣe nilu Gambia, Ivory Coast nile Potogi ati ni Idahọmi.

Asiko yi awọn agbado wa ngbo, awọn kokoro eṣu si jẹ ọta agbado, Jero, Ọka, baba, Ireke. Ẹ ma gbaradi nitori a ko mọ ọna ti awọn le ba yọ.


**Polowo Oja Re Sinu Iwe Eleti-Ofe Ki E Si Ma Ka Fun Irohin Aladun**




# Herbert Macaulay Ejonigboro



Oro mimo Olorun so wipe, ibukun ni fun eniti o se iranti Olododo, Alukurani si tun so wipe, ibukun ni fun eni ti o se iranti oku orun, awon angeli lorun yio ma se iranti oluwa re si ohun rere.

Osu ti a wa yi lo di odun mokanla ti ologbe Herbert Samuel Heelas Macaulay eni ti o gba oye nla C.E. nigba aiye re ti ku. On le okan pataki ninu awon ti o bere ise selu nilu Eko. On lo da akoko egbe iselu sile ti a npe ni, The National Demoncratic Party ni odun 1923, eyiti gbogbo ilu Eko lowe si nigbana.

On lo se atilehin fun Oloye Oluwa nigba na ti a npe ni Amodu Tijani, nipa oro ile ,e ti o mbe ni apapa, on lo si mu oloye ,a lo mo oba Gesi (King George Karun)

Anu se ni lati so wipe Makoli ku talku awon ara Eko fe lo egbe Demo lati fi ba ilu je. Sugbon bi Makoli ba ku, sibe, Makoli si ku sile.

Orin yi ni a leko fun awon to fe ba ilu Eko je. Orin najo orin Awo sugbon awon Onifa lo nlo o.

O gb'orile o j'eku o,
O gb'orilẹ o j'ẹja;
O gb'orilẹ ẹkun aṣeke
Ṣe ranti ilẹ ta jọ mu

# Isipaya Nipa Arun Jedi-jedi

Jẹdi-jẹdi jẹ arun kan ti o buru jọjọ ti ima ba tọkunrin tobinrin ja, ko si ẹniti arun na ko mba ja. Arun yi buru to bẹ gẹ ti o fi jẹ wipe, ẹniti arun na ba pọju lara rẹ ko ni le ṣe bi ọkunrin, o si ma ajẹki idi ẹni yọ irobo ṣode.

Ohun ti o nfa arun yi wa si wipe, bi enia ba njẹ adun pupọ, a ma jẹki arun yi tunbọ gbojikan lara enia. Ki nṣe okan didun ni kan lo nfa arun na wa Ẹgusi ni jijẹ pupo a ma fa a. Ẹpa tabi ororo ni jijẹ pupọ a ma le arun na loro.

Arun jẹdi-jẹdi a ma fa Igbẹ-ọrin, airi igbẹ ya. Ki enia ma yagbẹ ẹjẹ, tabi ki idi ma rin enia winni-winni. Ko si ẹniti a bi ti ko ni arun jẹdi-jẹdi lara. Ogidileje awọn enia ni arun yi ti pa danu, ṣugbọn awọn ọmọ ọwọ ni arun na pa pupọ ju.

Ọpọlọpọ awọn enia lo ti fi iwa ọmọ mi ikẹ, igẹ pa ọmọ wọn danu, nigbati arun yi ba nyọ ọmọ wọn lẹnu, ti ọmọ na si wa bẹrẹ si yọnu, kaka ki nwọn ṣe akiyesi ohun ti o fa idi kike ọmọ na, nwọn o ma ra okan didun fun. Ṣugbọn awọn obinrin ti o gbọn, a ma fi omigbona rọ idi ọmọ na, nwọn o si tun ma fun ni agbo mu. Ọlọrun ko maṣe jẹki agba tan lorilẹ.

## Kere o!

A ti ni erigirigi ogun German to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.

# Oba Olowo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Alaiyelu-Kabiyesi Oba Olowo, [illegible] je okan ninu awon awujo loba-loba ti o sin Alaiyeluwa oba Oni ile ife de ona lati fi han wipe ilu oyinbo ti Oba na lo je pelu inu didun awon oba ile Yoruba lati lo gba ominira bo wa si le.

# AKIYESI

## Lagos Executive Development Board

PLANNING CONTROL

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra ilẹ lati fi kọlọ si, tabi ẹnikan ti o nilẹ ti o si fẹ kọlọ sori rẹ, tabi ẹnikan ti o nile ti o si nfẹ tun ile na kọ, ni Eko nihin, a gba awọn ẹnibẹ niyanju wipe ki nwọn to ṣe ohunkohun rara, ki nwọn wa bere wo ni ile iṣẹ Town Planning Department ti Igbimọ Lagos Executive Development Board bawo ni agbogbo ibẹ ti ri pẹlu eto ilu ti nwọn nṣe, ki o si le mọ iru ile ti o yẹ ki o kọ sibẹ.

Ẹniti o ba fẹ ki o kọwẹ bere tabi ki on papa wa si Town Planning Department ti Igbimọ Lagos Executive Development Board ni opopo, Reclamation Road ni Eko lati agogo mẹjọ si agogo mẹwa owurọ lati ọjọ Monday titi di ọjọ Friday, ati lati agogo mẹjọ si mẹsan owurọ ni ọjọ Saturday

J. W. HENDERSON
Olori Igbimo L.E.D.B.



# CASORINA

## Fun Awon Omo Owo ati awon mo Kekeke

Egbogi fun Aigbọnsẹ Ọmọde. Jẹdijẹdi ati orisirisi ni aisan ti ima mu inu rirun wa fun Ọmọde.



Aigbọnsẹ daada ni ima mu orisirisi aisan miran ti ima yọ Ọmọde lẹnu jade. Ailesun dada, jija wọuranwọuran, ilọnu, jẹdijẹdi, igbona-Ọmọde, ati ọpọlọpọ aisan bawọnyi ni aigbọnsẹ daada ma nmu wa sara Ọmọde. CASORINA ni egbogi atata ti o dara lati lo fun Ọmọde fun awọn aisan wọnyi.

LILO RẸ—Ṣibi kekeke kan lẹmẹta lojọ pẹlu omi to lọ wọwọ.

IGO KAN ṢILE MEJI - ABỌ (2s. 6d)
AWỌN TI NPIN FUN TITA NI—

**THE ALBAN PHARMACY**
2, VICTORIA STREET, LAGOS NIGERIA.






## Ogun Aran (Ẹjo Inu)

Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buburu ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran, bẹni o npa ẹyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6d. Owo-Ọkọ si jẹ 1/-.

THE ẸGBA TRADING
ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.


# Kereni Odo Osun



Awọn enia kan lo sọ bayi, ninu Iwe Bibeli lati fi kẹgan awọn ọmọ Israeli ti Ọlọrun nfẹ wipe "Njẹ ohun rere kan ha le ti ilu Nasarẹti jade wa bi ? nigbati ohun rere na si de, nwọn ni ki nwọn jade wa wo ohun rere na.

Bakanna ni ọrọ ti Awolọwọ ti awọn apakan enia sọ pe ko le ṣe ohun kọkan, loni, awa ni igboiya lati sọ fun awọn enia na pe, ki nwọn jade wa wo iṣẹ ọwọ Oloye Awolọwọ. Lasiko ijọba tirẹ ni nwọn ṣe kereni yi sori odo Ọṣun. Kekere ati iṣẹbọrẹ ni eyiyi jẹ rinu iṣẹ Oloye na.

# Tani le ja awon alo yi ?

1 Arugbo ni mi, ṣugbọn bi o ba pin orukọ mi ọna meji, apa kini jẹ arugbo, apa keji jẹ koboko. Ki ni a ti npe orukọ mi?

2 Crisi ọbẹ kan ni mi, Bi a ba pin orukọ mi si meji apa kini jẹ nkan ti o tobi apa keji jẹ nkan bi Kumọ Ki ni orukọ mi?

3 Enia marun ngbe oku lọ si ọrun, nigbati nwọn de ẹnu bode, oku na dahun pe ki nwọn gbe on silẹ, ki on fi ẹsẹ ara on rin lọ si ọrun Tani oku ati awọn ti o ngbe oku lọ?

4 Crisa baba mi laelae, orisa baba mi lailai ojojumọ lo ngba ẹbọ, ki ni orisa na?


## FEMITONE

IDEAL TONIC for ANTE-NATAL & NURSING MOTHERS.

4s 6d

ANJORIN CHEMISTS Ltd.
116, King George Avenue, Yaba and Branches, Phone 44288.


# Owe Yoruba

Iduro ko si, fun ẹniti o gbe ọmọri odo mi.

Amokunkun ṣọle ti o wipe oju oba aiye kori on, nje bi oju oba aiye ko ri ọ ti Ọba ọrun ko ha nwo ọ bi ?

... & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box O. 467 Lagos Phone 2335